# Education Digital Equity Initiative

# ÌWÉ ÈTỌ̀ ÌKỌNI

**ỌNÀ ÀBÁYỌ OLÓWÓ PỌỌKÚ FÚN ÌKẸKỌỌ ONÍDÍGÍTÀ (FÚN ÀWỌN AKẸ KỌ Ọ NÍ ILÉ Ẹ KỌ ÌGBÈRÍKO)**



Agbátẹrù:

UK aid from the British people | Foreign, Commonwealth & Development Office

Láti ọwọ́:

AREAi

# NÍPA AREAi

A dá a sílẹ̀ ní ọdún 2014, wọn sì fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní Nàìjíríà abẹ́ àjọ Corporate Affairs Commission (CAC) ní 2017, Aid for Rural Education Access Initiative (AREAi) jẹ́ àjọ tí kò rọgbọkú lé ìjọba, fún àwọn àjọ tí ó ń ṣe iṣẹ́ pẹ̀lúàwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí kò ní ohun-èlò tí ó tó àti àwon agbègbè tí wọn yàn ní pọ̀sì, nípa kíkún wọn lọ́wọ́ pẹ̀lú èròjà ìmọ̀ ẹ̀rọ̀àti àwọn ohun amáyédẹrùn láti ṣe ìgbéléwọn àbájáde ìkẹ́kọ̀ọ́ àti pípèsè ẹ̀kọ́ tí ó pójú owó fún àwọn mẹ̀kúnnù, àwọn ọmọ aláìnípá àti àwọn ọ̀dọ́ tí ó wá láti ìdílé tí owó péréte ń wọlé fún. Láti ìgbà ìdásílẹ̀ rẹ̀, AREAi ti ṣe àgbékalẹ̀ ara rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú àwọn àjọ ètò ẹ̀kọ́ tí ó gbawájú ní Nàìjíríà pẹ̀lú àfo-júsùn wọn nípa ṣíṣe iṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn asíwájú àdúgbò àti àwọn àjọ ìjọba láti àwárí ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ alápàrò-kan-ò-ga-jùkan-lọ àti ètò ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pírámárì àti sẹ́kọ́ńdírì tí owó tí ó tó kò wọlé fún, àwọn ọmọdé tí ọ̀dọ̀ wọn nira láti dé àti àwọn agbègbè ìgbèríko. Pẹ̀lú àwọn kókó àfojúsùn wọn lórí níní ẹ̀tọ́ sí díjítà, ọgbọ́n ìmọ̀-ọn-kọ-mọ̀-ọn-kà, ètò ẹ̀kọ́ọmọbìnrin àti àtinúdá àwọn ọ̀dọ́ nínú ètò ẹ̀kọ́, onírúurú ètò àjọ náà ti la ipa lórí àwọn ènìyàn tó jẹ́ àǹfààní rẹ̀ tí wọn lé ní ẹgbẹ̀rún mẹ̀rìndínlógún (16,000) káàkiri agbègbè mẹ̀tàlélógún ní àwọn ìpínlẹ̀ tí ó tó mẹ́jọ ní orílẹ̀-èdè yìí.

Adarí iṣẹ́ àgbéṣe, aláṣẹ elétò: Gideon Olanrewaju
Aṣíwájú ẹgbẹ́ iṣẹ́ àgbéṣe: Yetunde Abiodun Omotosho
Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ iṣẹ́ àgbéṣe: Olajide Charles Falajiki, Godwin Osama, Ifeoluwa Ariyo-Agbaje, Motunrayo Fatoke Olùya-fọ̀tò: Faje Kashope, Faith Oguche, Jennifer Bekes
Olùyà-àwòrán: Olamide Agunbiade, Aderemi Temitope
Kàn sí wa: info@areai4africa.org, +2347061169861
Ayélujára wá: www.areai4africa.org , https//equity.areai4africa.org/
Àdírẹ́sì wá: Impact Cove, No 4 Sefado Close Wuse 2 Abuja Nigeria.

© 2021

# ÀGBÉYẸ̀WÒ IṢẸ́ ÀGBÉṢE

The Education Digital Equity Initiative jẹ iṣẹ àkànṣe ajẹmọ-ìròyìn èyí tí ó ń rí sí àìlo díjítà pẹlú pípèsè àti pípín oríṣìírísi ẹrí, èròjà ẹkọ gbígbòòrò tí wọn ń ṣe àfihàn àwọn ìgbésẹ àti èrò tí ó rọrùn fún àwọn ilé-ẹkọ ìgbèríko, àwọn agbègbè tí ó ta kéte, àtinúdá ajẹmágbègbè àti àwọn ìdílé tí owó péréte ń wọlé fún láti ni àǹfààní àwọn ohun-èlò ìkẹkọọ òkèèrè, ohun- èlò ẹkọ orí ayélujára àti àǹfààní sí ìkẹkọọ onídíjítà lẹyìn àjàkálẹ àrùn COVID19. Iṣẹ yìí ṣe àmúlò ìlànà ìlò onírúurú àwon agbátẹrù láti ṣe ètò níní ẹtọ sí díjítà nípasẹ ìwádìí ìṣòdiwọn àti ọnà ìgbàròyìn fún ṣíṣe ètò ìtanilólobó nípa àwọn ẹrọ tí wọn ní ipá fún ìmúdúró ìmúgbòòrò ìbẹrẹ, díjítà ìkẹkọọ àti ìgbẹkọ olówó pọọkú fún àwọn mẹkúnnù. Àjọ United Kingdom's Foreign, Commonwealth and Development Office ni ó ṣe ètò ìnáwó lórí iṣẹ yìí, ní abẹ ilé-iṣẹ Prosperity Fund's Digital Access Programme.

# NÍPA ÌWÉ ÌKẸ́KỌ̀Ọ́ YÌÍ

Ìwé yìí ṣe àfihàn onírúurú àpẹẹrẹ ìkẹ́kọ̀ọ́-inú-ilé àti ọ̀nà àbáyọ sí ìkẹ́kọ̀ọ́ òkèèrè láti ṣe ìkúnwọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó wà ní ìgbèríko àti àwọn agbègbè tí ó ta kété láti jẹ kí wọ́n ní àǹfààní sí àwọn èròjà ìkẹ́kọ̀ọ́ tàbí kí wọn kópa nínú ètò ìkẹ́kọ̀ọ́ yìí. A ṣe àfihàn mẹ́sàn-án nínú àwọn ìkànnì ìkẹ́kọ̀ọ́ òkèèrè tí kò lo íntánẹ́ẹ̀tì, tí ó tún jẹ́ olówó pọ́ọ́kú, kí ó lè tàn káàkiri, kí àwọn akẹ́ kọ̀ ọ́ sì lè ṣe àmúlò rẹ̀ . À lérò pé ṣíṣe àmúlò ìwé yìí yóó ṣe àdínkù àìní ní àǹfààní sí àwọn ojúlówó ìròyìn lórí ìlànà ìkẹ́ kọ̀ ọ́ láìlo nẹ́ tíwọ̀ kì ní agbègbè kọ̀ ọ̀ kan. A tún rọ̀ àwon aṣíwájú àwùjọ, òbí, olùkọ́ , àti ọ̀ gá ilé-ẹ̀ kọ́ láti tẹ́ wọ́ gba àwọn èrò tí a ṣe àfihàn nínú ìwé yìí láti jẹ́ kí àwọn ọmọ àti akẹ́kọ̀ọ́ wọn jẹ àǹfààni ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́ yìí.

# NǸKAN MÉSÀN-ÁN PÀTÀKÌ NÍPA ÌKÀNNÌ ÌKẸKỌ̀Ọ́ ONÀ JÍJÌN OLÓWÓ-PỌỌKÚ TÍ KÒ LO ÍŃTÁẸẸTÌ

| OHUN-ÈLÒ | ÀWỌN TÍ A FOJÚ SÙN FÚN LÍLÒ | ÀNFÀÀNÍ ÀTI ÀLÉÉBÙ | IYE |
|---|---|---|---|
| Rédíò | Akẹkọọ Pírámárì àti Sẹkọńdírì | • Kò nílò íntánẹẹtì<br>• Ànfààní sí i lè má kárí<br>• Ó fi àyè gbà èsìn lè má dára | Owó péréte. |
| Tẹlifísàn | Akẹkọọ Pírámárì àti Sẹkọńdírì | • Kò nílò íntánẹtì<br>• Ó jẹ àpapọ ọdíò àti àwòrán | Ó wọn láti ni fún akẹkọọ. Ìdílé lè ní in. |
| Ìwé àti gègé tí ó ń sọrọ | Akẹkọọ Pírámárì | • Kò nílò íntánẹtì<br>• Kò wọn tó tábílẹtì<br>• Ó fi ààyè gba ìkẹkọọ ní ọpọ èdè. | Odidi kan tí ó ní gbogbo èròjà jẹ 30,000 naira. |
| Ìmọ-Ẹrọ Àtẹjíṣẹ | Akẹkọọ Sẹkọńdírì | • Kò nílò ìntánẹtì<br>• Kò nílò fóònù olówó-ńlá | Ó wà láàrin 300 sí 500 náírà láti ní ànfààní sí i lósoosù. |
| Ohun-èlò ìkẹkọọ nílé | Akẹkọọ Pírámárì àti Sẹkọńdírì | • Kò nílò íntánẹtì<br>• Kò nílò ohun-èlò ẹrọ Kankan | Owó péréte |
| Tábílẹtì Ìkẹkọọ | Akẹkọọ Pírámárì àti Sẹkọńdírì | • Ó lè nílò íntánẹtì<br>• Ó lè gba àkóónu púpọ | Ó wà láàrin 20,000 náírà sí 30,000 náírà |
| Ìkàwé Onídíjítà | Akẹkọọ Pírámárì àti Sẹkọńdírì | • Ó lè nílò íntánẹtì<br>• Ó ní ìwé, fídíò àti ayò | Nnkan bí 5000 náírà |
| Awò Afẹfẹ | Akẹkọọ Sẹkọńdírì | • Kò nílò ìntánẹtì | Ó wọn láti ni fún akẹkọọ. Ilé-ẹkọ lè ní in |
| Ìkànnì Ohun-Èlò Ìkẹkọọ | Akẹkọọ Sẹkọńdírì | • Ó lè nílò íntánẹtì | Ọfẹ |

# Ìwé àti Gègé Ìkọ́wé tí ó ń sọ̀rọ̀

Ìwé àti gègé-ìkọwé tí ó ń sọrọ ni gègé-ìkọwé onídíjítà àti àkànṣe ìwé títẹ.
Nígbà tí gègé bá kan ohun tí wọn kọ tàbí àwòrán inú ìwé, yóó ka ohùn tí ó bá bá a mu síta, àti àwọn ayò tí ó wọni lára, ìbéèrè, títúmọ èdè púpọ, abbl. Ìwé àti gègé-ìkọwé tí ó ń sọrọ ran àwọn ọmọdé lọwọ gbòòrò nínú ìmọ mọ-ọn-kọ- mọ-ọn-kà àti òǹkà nípasẹ àkóónú ìkẹkọọ tí ó ní ààtò. Onírúurú èdè ni wọn fi kọ àwọn ìwé náà, àwọn èdè bí French, Arabic, Spanish, Hausa, Igbo, and Yoruba. Ó ti wà ní orílẹ-èdè Nàìjíríà, ènìyàn sì lè rí i rà ní owó péréte bí ẹgbẹrún mẹẹẹdọgbọn náírà (25,000naira).

Láti ra ìwé àti gègé-ìkọ wé tí ó ń sọ rọ , ò lè kàn sí http://maviseducation.com/store/


Olúkọ wa, láti ìgbà tí wọ n ti ti ilé-ẹkó ni àwọn ọmọ wa tí dá ẹkọ èdè Gẹẹsì àti ẹkọ Ìsirò dúró. Báwo ni ẹ ṣe lè ràn wá lọwọ?
Ẹ má ṣe ìyọnu Alhaja àti Màmá Chinoso. Mo tún gbọ pé wọn ò lè dara pọ mọ àwọn kíláàsì ìkẹkọọ lórí Zoom tàbí Microsoft Teams.


Ẹrọ tí ó wà lọwọ mi yìí ni wọn pé ní Gègé tó ń sọrọ. Kò nílò íntánẹẹtì láti ṣíṣẹ. Danladi ati Chinoso lè lò ó láti ní ìmọ mọ-ọn-kọ-mọ-ọn-kà àti ẹkọ ìsirò àti látikọ ẹkọ ní ìlànà ìṣèré tí ó wọni lára.
Èyí gbọdọ dára. Mo tún rí i pé o tún ní ìbọtí agbohùn. Dájúdájú, màá ra ọkan fún Danladi. Yóò tẹsíwájú láti máa lò ó láti fi kọ ẹkọ mọ-ọn-kọ-mọ-ọn-kà.


Danladi, ṣé ohun tí o ti ń lò láti kọ ẹkọ láti ìgbà tí a ò ti lọ sí ìlè-ẹkọ nìyí?
Bẹẹ ni Adewale!: Ó tó ọgọrùn-ún ìwé tí ó wà nínú ìwé ti ń sọrọ. Nípa lílò ó fún ìkẹkọọ, mo ti lè sọ àwọn gbólóhùn kọọkan, dáhùn ìbèère, mó sì lè ka àwọn ayọka inú akáye. Mo fẹràn gègé ìkọwé rẹ nítorí pé ó lè sọ Hausa, Gẹẹsì, Yorùbá àti Ìgbò.
Mo lérò pé gbogbo àwọn akẹkọọ nínú kíláàsì wa níláti mọ nípa èyí. Màá sọ fún ìyá mi láti ra ọ kan fún mi.


Ó dára láti ki yín káàbọ padà láti ìsinmi ọlọ jọ gbọọrọ. Mo lérò pé ọpọ nínú yín kọ ẹkọ nílé ní àsìkò ìsinmi?


Bẹẹni Àntí, mo tí ń kọ bí wọn tí ń sọ àti bí wọn ti ń kọ ìwé ní èdè Hausa àti Faransé nípa lílo gègé-ìkọwé ti ó ń sọrọ yìí. Mavis Talking BookTM (MTB) ni gègé ìkọwé díjítà (Mavis Pen) àti àkànṣe ìwé títẹ. Nígbà tí gègé ìkọwé náà bá kan ọrọ tabí àwòrán nínú ìwé náà, gègé-ìkọwé náà yóó ka ọrọ ibẹ jáde. Ó ní ayò tí ó wọni lára, àwọn ìbéèrè, titúmọ ọpọlọpọ èdè, ìtàn, orin, abbl.
Hòò, mo mọ nípa ìwé àti gégé-ìkọwé tí ń sọrọ náà. Wọ n̄ ṣe àgbékalẹ rẹ ní ìbámu pẹlú kòríkúlọọmù ètò ẹkọ Náìjíríà. Mo lérò pé ó yẹ kí gbogbo yín ní ìwé àti gégé-ìkọ wé náà. Y óó ràn yin lọ wọ lásikó ikẹkọọ àkọ kún- ẹkọ .

# Ìmò Èrò SMS àti USSD



Bí a ó ṣe lò ó

Ǹjẹ o mọ pé pẹlú fóònù onítọọsì kékeké tí kì í lo dátà tàbí íntánẹtì, ó rọrùn fún ẹ láti fi ọrọ wérọ pẹlú olùkọ káàkiri orílẹ-èdè Nàìjíríà? Ṣùgbọ n BÁWO NI ?

- Ní Nàìjíríà, o lè tẹ *347*774# tàbí *3549# láti ní àǹfààní sí onírúurú nǹkan tí ó wà nínú ohun-èlò ìkọ ni.
- Ò lè ka iṣẹ kíláàsì yín, wo íntánẹtì láìlò dátà, gba ìbéèrè ìgbéléwọn lórí ìbéèrè èwo-ni-ìdáhùn àti ìbéèrè agbàròkọ - nípa àtẹjíṣẹ, kí o sì gba èsìn lórí àwọn ìdáhùn rẹ láti mọ bóyá ó tọnà tàbí ó kùnà.
- Ò lè san owó tí ó kéré bi ọgọ rùn-ún náírà (100 naira) ní ọ ṣọ ọ ṣẹ àti ọ ọ dúnrun náírà ní oṣooṣù (300 naira) gẹ gẹ bí owó ìlò • Ò lè kọ ẹkọ pẹlú èyíkèyìí èdè ìbílẹ tàbí kí o yan èyíkéyìí iṣẹ tàbí àkòrí tí ó wù ọ ní ìgbà tí ó bá ń lo USSD tàbí SMS.


Ẹyin akẹ́kọ̀ọ́ mi ọ̀wọ́n, àsìkò ìdánwò àṣekágbá yín tí súnmọ́. A ò ní sí ilé-ẹ̀kọ́ fún atúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ àti ìkẹ́kọ̀ọ́. A ti gbé gbogbo ìkẹ́kọ̀ọ́ lọ sí orí ayélujára.
Ṣùgbọ́n, báwo ni a ó ṣe ka ìwé àti àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ kí á lè ṣe àṣeyege nínú àwọn ìdánwò wa? A kò ní kọ̀npútà, tábílẹ̀tì tàbí fóònù ńlá tí a lè fi kọ́ ẹ̀kọ́ lórí ayélujára.


Ẹ kò nílò láti ṣe ìyọnu. Mo mọ ọnà àbáyọ tí ẹ lè gbà láti gbáradì fún ìdánwò yín. Ó ṣiṣẹ lórí àwọn fóònù onítọọṣì kékeré tí kò nílò dátà. Pẹlú pípe kóòdù *347*774# tàbí *3549#, o lè bèèrè ìbéèrè yòówù lọ wọ àwọn olùkọ jákèjádò Náìjíríà. Ó tún lè ní àǹfáàní sí àwọn ohun-èlò ìkẹkọọ, o sì tún le wá nǹkan lórí ayélujára láìlo íńtánẹ́ẹ̀tì.


Bàbá mi, ẹ jọwọ ṣé mo lè lo fóònù Nokia 3310 yín? Mo fẹ fi kàwé fún ìdánwò UTME mi nípa fífi àwọn ìbeere ìdánwò tí wọn tí ṣe kọjá dánra wò pẹlú ìlò DigiLearns SMS.


Frank, mo ní ọpọ ìbéèrè lórí àwọn ẹkọ tí wọn kọ wa àti ọpọ ìdánrawò tí mo ti ń ṣe pẹlú ìwé kíkà lórí ẹrọ tí Olóyè sọ fún wa nípa rẹ.
Ǹjẹ òlèrànmílọwọ,jọwọ?


Abdullahi, ìyẹn rọrùn. Ò ó tẹ kóòdù láti lo “béèrè-lọwọ-olùkọ kan” láti fi ìbéèrè rẹ ránṣẹ sí olùkọ yòówù fún ogún iṣẹ. Wọn yóó dá ọ lóhùn kí ó tó pé ọgbọn ìṣẹjú pẹlú àtẹjíṣẹ.
Ìyẹn dára gan-an, Frank. Mo lè lo èyí pẹlú “offline google feature” èyí tí ó jẹ kí á ní àǹfààni wíwá ìtumọ ọrọ lórí ayelújá láìlo íńtánéẹ ṭ ì.


Ó dá mi lójú pé Ọgbẹni Solomon yóó lè dáhùn ìbéèrè Kẹmísírì yìí fún mi. Jẹ kí n lo ẹkọ díjítà.
Níbo ni ọgangan híhó ẹtanọọ?
Ìbéèrè ńlá ni Frank bèèrè yìí, jẹ kí n dá a lóhùn kíákíá.
Ọ gangan híhó ẹtanọọ ni 78.5°C

# Èròjà Ìkẹ́kọ̀ọ́ Nílé

## (Títẹ ẹdà Ohun-èlò Ìdáwèékà)

Láti mú ìtẹsíwájú tí ó gbòòrò bá ẹkọ àwọn ọmọdé nílé àti èròngbà lórí àtipadà sí ilé-ẹkọ, a lè kún àwọn akẹkọọ lọwọ pẹlú ìwé ẹkọ ojúkojú, ìwé kíkà, àti gbogbo èròjà ẹkọ ti a ṣe ẹdà, è, àti gbogbo èròjà ẹkọ ti a ṣe ẹdà, èyí o lè ṣe ìrànwọ ètò ìkàwé fún wọn, kódà bí kò sí íńtánẹ́ẹ ṭì. Àwọn akẹkọọ lè ṣe àgbékalẹ àwọn èròjà yìí fúnra ara wọn tàbí pẹlú ìkúnwọ àwọn òbí, ẹgbọn, olùkọ tàbí alágbàtọ. Bí wọn bá bá ọ ṣe é dáadáa ohun-èlò ìkàwé nílé kan lè jẹ àkópọ ẹkọ tí akẹkọọ kọ ní ilé àti ilé-ẹkọ.


Ẹ yin akẹkọọ ọwọn, Mo rí lẹtà tí ẹ kọ láti bèèrè fún ìrànwọ gbà. Ẹ fẹ kí a kún-un ẹyin àti àwọn ọrẹ yín lọ wọ pẹlú àwọn ohun-èlò ìkàwé ní àsìkò ìgbélé. Ilé-ẹkọ tí fún yín ní àwọn èròjà ìkẹkọọ nílé.


Chidinma, gbogbo iṣẹ tí ó yẹ kí a ṣe ní kíláàsì ni a ti tẹ ẹdà wọn jáde láti lè ràn wá lọwọ nínú ìwé àdákà nílé.
O ṣeun gan-an Ọlámidé. Màá kó wọn nísinsìnyí, màá sì tò wọ n láti pín wọn fúngbogbo àwọn alẹgbẹ wa ní kíláàsì.


Nísinsìnyí tí wọn ti ṣe ẹdà àwọn ìwé ìkẹkọọ fún wa, a ó pàdé ní ilé ìkẹkọọ agbègbè. A ó jọ kọ ẹkọ inú ìwé náà papọ kí ilé- ẹkọ tó wọlé.


Màámì, èyí ni èròjà ìkẹ́kọ̀ọ́-ilé mi. Mo fẹ́ kọ́ ẹ̀kọ́ nípa "Pollination", èyí tí ó jẹ́ àkòrí tí ó kàn nínú kíláàsì wa.
Wo ìyàtọ̀ láàrin Cross-Pollination and Self-Pollination ni. Ṣé ó yé ọ? Ǹjẹ́ o fẹ́ kí n ṣe àlàyé rẹ̀ fún ọ? Biology ni iṣẹ́ tí mò yàn láàyò.

# Tábílètì Ìkékọ̀ọ̀

Tábílẹ̀tì ìkẹ́kọ̀ọ́ ni àwọn ẹrọ díjítà tí wọn ti kó àwọn èròjà kọ̀ǹpútà kan sí nínú, tí wọn sì ṣe ètò rẹ fún kíkọ àwọn ọmọdé ní ẹkọ tó yè koro, pàápàá jù lọ, àwọn tí wọn wà ní ìgbèríko níbi tí kò ti sí íntánẹ̀tì to já gaara ati ibi tí kò tilẹ̀ sí rárá. orísìírísì ni ẹyà tábílẹ̀tì tí ó wà, èyí ti wọn lè ṣiṣẹ yálà pẹlú nẹ̀tíwọ̀kì tàbí láìsí nẹ̀tíwọ̀kì.

Ní Nàìjíríà, ULesson jẹ àpẹẹrẹ tó ṣe déédé fún tábílẹ̀tì tí ènìyàn lè fi ní àǹfààní sí àwọn ohun-èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pírámárì àti sẹ̀kọ́ndírì. Iye rẹ ni ẹgbẹ́rún mẹ́ta àbọ̀ náírà (3500 naira) ní oṣooṣù fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń gbé ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.


Ẹ yin akẹkọọ ọwọn, mo jẹ aṣojú àjọ abẹlé kan tí kò rọgbọkú lé ìjọba. Mo wà níbí láti wá fi bí wọn ṣe ń lò tábílẹtì ìkẹkọọ hàn yín. A ní onírúurú fọnrán fídíò àti ọdíò ìkẹkọọ nínú rẹ. Yóó jẹ kí ó rọrùn fún ẹyin àti àwọn ọrẹ yín láti jọ kọ ẹkọ papọ àti láti dá ẹkọ kọ.


Àwọn tábílẹtì wọnyí ní ọpọlọpọ àkóónú láti kọ ẹkọ àwọn èdè tuntun. Mo sì ń ka ìwé lọwọ lórí ẹkọ èdè Faranṣé.
Bẹẹ ni, àwọn fídíò náà ní ẹkúnrẹrẹ àlàyé. Mó ń wò bí mo ṣe lè dáàbò bo ara mi ní àsìkò àjàkálẹ àrùn.


Kínni ẹ ti ṣètò láti kún wa lọ wọ ní ọdún yìí gẹgẹ bí alága Ẹgbẹ Òbí àti Olùkọ?
Èmi àti àwọn òbí yòókù ti gbèrò láti ṣiṣẹ pẹlú ilé-iṣẹ kọǹpútà abẹlé kan. A ó fún ilé-ẹkọ ní ọpọ ẹbùn àwọn ẹrọ tábílẹtì. Àwọn ọmọ wa lè lò ó láti kọ ẹkọ ní ilé àti ní ilé- ẹkọ.


Inú mi dùn pé a lè tẹsíwájú nínú ẹkọ wa nílé láti ìgbà tí àjàkálẹ àrùn ti bẹrẹ. Gbogbo àwọn ìwé kíkà àti ìwé ẹkọ wa ni ó ti wà lórí ẹrọ tábílẹtì yìí.
Mo fẹràn tábílẹtì náà síí nítorí pé n kò nílò láti lo íntánẹtì kí ó tó ṣiṣẹ, ó sì tún lè gba iná sí ara láti ara òòrùn nípàṣẹ ojú ṣólà rẹ.

# Ohun-èlò Ìkàwé Díjítà



Ohun-èlò Ìkàwé díjítà jẹ ohun-èlò ẹrọ ìkàwé èyí tí ó ní ọpọ yàrá ìkàwé ohun-èlò ìkẹkọọ díjítà tí ó jẹ kíkà ní ọfẹ lórí, èyí tí àwọn akẹkọọ lè kàn sí ní àwọn agbègbè tí kò ní ohun-èlò ní àrọwọtó. Ó fara jọ ohun-èlò ìkàwé e-book èyí tí ó máa ń jẹ kí ó kó ọpọlọpọ ìwé ní àsìkò kan náà, kí ó sì kàn sí ọpọlọpọ yàrá ìkàwé lórí ẹrọ kékeré tí kò tó odidi ìwé kan, tí iná tí o bá fi sí i lẹẹkan ṣoṣo lè lò tó ọṣẹ kan kí ó tó kú, kí ó sì lè jẹ kí o lè kàwé pẹlú ìrọrùn ju ti tábúlẹtì tàbí fóònù lọ. Fún àpẹẹrẹ, World Reader pèsè níní àǹfààní sí ọ pọ lọpọ àwọn ojúlówó ìwé díjítà káàkiri àgbáyé ní ọ fẹ nípasẹ ohun-èlò ìkàwé díjítà rẹ, èyí tí kò nílò íntánẹtì láti kàn sí wọn.

Àpẹẹrẹ ìwé díjítà tí ó jẹ olówó pọọkú ni Kindle Paper White tí Amazon èyí tí ó jẹ ẹgbẹrún mẹẹẹdógún (15,000) lórí ìkànnì ayélujára abẹ lé bíi Jumia tàbí Konga.


Bọdá Muda, ẹ jọwọ ṣe ẹ lè ràn mí lọwọ láti fún mi ni ohun- èlò ìkàwé tí ó wà lórí ẹrọ ìkàwé yín? Mo fẹ má aka ìwé ní ọfẹ nípa eré ìdárayá, èto ìkọni, ẹsìn, ìwé ìtàn àròsọ alátinúdá, àti ìwé ìtàn abáyému?
Bẹ ẹ ni, màá ràn ọ lọ wọ . O tún lè kàwé káàkiri àgbàyé pẹlú oríṣìí èdè mẹrìnlélógóji, lórí ẹka iṣẹ àádọrin. Ohun-èlò náà tún lè ṣe iṣẹ láìsí nẹtíwọọkì.


Nísinsìnyí tí mo ti ní ohun-èlò ìkàwé, màá bá Zuri àti Zara nínú ìlànà iṣẹ Literature-in-English èyí tí wọn ní lórí ẹrọ ayára bí àṣá wọn.




Awò afẹfẹ jẹ ọnà láti rin ìrìn-àjò láìlo ohunkóhun yàtọ sí agbára ìmọ ẹrọ. Pẹlú ìbọrí VR yóó jẹ kí o wo ibikíbi lótí afẹfẹ gẹgẹ bí ẹni pé onítọhún wà níbẹ gan-an, tàbí kí o ta ayò gẹgẹ bí i pé o wà nínú rẹ. Awò afẹfẹ jẹ ọnà ìmọ-ẹrọ ìgbàlóde tí ó ń ran àwọn ọmọdé lọwọ láti kọ ohunkóhun lórí afẹfẹ láti ibikíbi tí wọn bá wà ní bí ó ti wà nínú ìrírí àgbáyé. Ó ṣe àfihàn bí nǹkan ṣe rí ní ojú-ayé, kí ó sì fún ẹni tí ó ń lò ó ní wíwò ní ọnà àrà tí ó fara jọ tàbí yàtọ sí bí ó ṣe rí lójú ayé, láti jẹ kí ẹni tí ó ń lò ó láti kópa nínú ẹkọ ajẹmọ-àyẹwò.


Sir, ẹ jọwọ a nílò ìrànlọwọ yín láti ṣe ìgbáradì fún àyẹwò ṣáyẹǹsì wa, ṣùgbọn kò sí ohun-èlò ní ilé-ẹkọ.
oh, ẹ má ṣe ìyọnu lórí ìyẹn. Ǹjẹ, o ti gbọ nípa VR rí?
Àbí Awò Afẹfẹ ni ẹ ń sọ?


Ó dájú pé mo mú ife-àyẹwò ní ọwọ mi.
Sir, ẹ jọwọ mo wòye pé a wà nínú YÀRÁ ÀYẸ WÒ!
Ibi tí ò ń lọ nìyẹn! Káàbọ sí yàrá-àyẹwò Kẹmísírì.



# Tẹlifísàn

Àwọn ọmọdé lè kọ ẹkọ nípa lílo tẹlifísàn nípasẹ fídíò ìfọrọwérọ, ètò orí tẹlifísàn tàbí àgbàsílẹ tí olùkọ lè fi hàn ní àsìkò ìdánilẹkọọ. Ìjọba tún lè ṣe ètò kí wọn sì gbé ẹkọ tí wọn ti gbà sílẹ sí orí afẹfẹ káàkiri ilé-iṣẹ tẹlifísàn ní gbogbo ìpínlẹ. Lọpọ ìgbà, olùkọ máa ń kọ ẹkọ lórí afẹfẹ lórí tẹlifísàn àwọn akẹkọọ yóó sì dara pọ mọ ẹkọ lórí afẹfẹ láti ilé tàbí ààyè ìkẹkọọ wọn. Fún ìdí èyí, agbègbè kọọkan lè ṣe ìdánilẹkọọ lórí afẹfẹ nínú àdàmọdì kílààsì tàbí lórí ètò orí afẹfẹ àti ohun- èlò tí wọn ti gbà sílẹ. Nínú ìfọrọwérọ ẹkọ orí tẹlifísàn, àwọn ọmọdé lè kọ ohunkóhun, nígbàkúùgbà àti níbikíbi, kódà ní àgbègbè wọn ní ìgbèríko àti a`won ibi tí ó nira láti dé.


Ẹ jọwọ, mo ní ìbéèrè? Kín ló dé tí ẹ ń gba àwọn ẹkọ kílàásì yìí sílẹ, Àǹtí?
Ní àsìkò yìí tí ilé-ẹkọ ti ń wà ní ìtì pa, gbogbo àwọn ìdánilẹkọọ yìí yóó jẹ kíkásílẹ ṣáájú láti pín-in káàkiri àwọn ilé-iṣẹ tẹlifísàn ìbílẹ. Ó wà fún ẹyin àti àwọn akẹgbẹ rẹ tí kò lè lọ sí ilé-ẹkọ . Gbogbo yín lèyí tẹlifísàn yín sí ìkànnì náà láti wò ó ní ojoojúmọ láti agogo méjìlàọsán.
Ẹ ṣeun Àǹtí, inú mi dùn pé a lè wo yín kí a sì béèrè àwọn ìbéèrè wa ní ìparí ètò ẹkọ.




Nísìnsìnyí tí mo ti ká gbogbo àkòrí mẹ̀rìndínlógóji inú ìlànà ètò ẹkọ iṣẹ mi sí fọnrán fídíò, àsìkò ti tó láti fi ránṣẹ káàkiri sí àwọn olóòtú ilé- iṣẹ tẹlifísàn ti ìpínlẹ láti gbé e sí orí afẹfẹ.


Mo fẹràn ètò orí tẹlifísàn yìí. Aǹti yìí ń ṣe àlàyé tí ó yéni yéké-yéké, èyí tí ó dabí ẹni pé kíláásì la wà.
Mo ti mọ ìsirò Algebra dáadáa báyìí, mo sì lè ṣe ìsirò *linear equations*.
Mo ní ìbéèrè tí mo fẹ bèèrè lórí fọ múlà fún ìsirò *Quadratic equation*.
Ò lè pè sí orí 07099887766 lẹyìn ẹkọ láti bèèrè ìbéèrè rẹ.

# Ìkànnì Ohun-èlò ìkẹ́kọ́ọ̀

Open Educational Resources (OER) jẹ èyíkéyìí èròjà ìkẹkọọ tí ó wà ní ọfẹ fún àwọn olùkọ àti akẹkọọ láti lò, tún un ṣe, pín in àti àtúnlò rẹ. láìná owó kankan, àwọn akẹkọọ lè kọ ẹkọ nípa lílo àwọn ìkànnì yìí. Díẹ nínú àwọn ìkànnì tí a ti lè ní àǹfààní sí Open Educational Resources (OER) ni Wikipedia, Wikimedia àti Wikibooks.


Ọgá Kọpà, abúlé tí ẹ ń lọ yìí kò ní íntánẹ́ẹ̀tì o. Báwo ni ẹ ó ṣe lè kọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yín?
Ọgá dírẹ́bà, mó ni ọpọlọpọ ohun-èlò ìkẹ́kọ̀ọ́ lórí ẹrọ ìbánisọrọ mi, èyí tí mo ti gbà sílẹ̀ tí mo sì lè lò láìlo dátà.


Kọpà, ẹ sọ fún wa pé àwọn ìkànnì kan wà tí a ti lè ni àǹfààni sí ìwé, ìtàn, àyò lọkan-ò-jọkan ní ọfẹ?
Bẹẹ ni, ọpọlọpọ wọn wà tí ẹ ti lè ní àǹfààní sí wọn lórí èyíkéyìí ẹrọ ìbánisọrọ tàbí ohùn-èlò mìíràn. Fún àpẹẹrẹ, ẹ jẹ kí a wo Wikimedia lórí ẹrọ ìbánisọrọ mi.




Ìlo rédíò fún ìkẹ́kọ̀ọ́ ṣáábà máa ń jẹ́ ọ̀nà ìtànkálẹ̀ ìròyìn, ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ́ ìrànwọ́ láti tan ìròyìn ká ọ̀dọ̀ ọ̀pọ̀ ènìyàn. Yàtọ̀ sí pé kò nílò íntánẹ́ẹ̀tì, ó jẹ́ owó pọọku, kò sì tún fi àkókò ṣòfò. Kíkọ́ àti gbígba ẹ̀kọ́ lórí rédíò jẹ́ rọrùn fún ìforọwérọ nígbà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ń forọ wérọ ní àsìkò ìkẹ́kọ̀ọ́ orí rédíò pẹ̀lú olùkọ́ orí rédíò, ẹ̀dá orí rédíò, olùkọ́ kíláásì ìkẹ́kọ̀ọ́ tiwọn àti láàrin ara wọn. Àwọn lè pè akẹ́kọ̀ọ́ sí orí ètò lórí rédíò láti béèrè ìbéérè lọ́wọ́ olùkọ́, kí wọn sì gba ìdáhùn sí ìbéérè wọn ní ìlànà kan náà. Ìjọba ìpínlẹ̀ lè ṣe àgbékalẹ̀ àti àgbàsílẹ̀ ẹ̀kọ́ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gírédì kìn-ín-ní sí ìkẹ́fà kí wọn sì tàn wọn ká nípasẹ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ rédíò agbègbè kọ̀ọ̀kan.

## Àpẹẹrẹ Ètò Ẹkọ Orí Olójoojúmọ Jákèjádò Nàìjíríà

| Orí Rédíò | Ọjọ àti àkókò | Isẹ Àfojúsùn |
|---|---|---|
| Radio Nigeria Enugu 92.9FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Ẹtì 11am – 12pm | Kílààsì Pírámárì |
| Ekiti 91.5 FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Ẹtì 3.10pm – 4pm | Kílààsì Pírámárì |
| Wazobia FM 95.1FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Ẹtì 12pm – 1pm | Kílààsì Sẹkọńdírì |
| Eko 89.7FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Ẹtì 10:30am – 1pm | Kílààsì Pírámárì 3, 4, 5 àti 6 |
| Freedom FM 99.5FM Kano | Ọjọ Rú sí Ọjọ Ẹtì 11:30am – 12:30am | Kílààsì Sẹkọńdírì |
| Naija 102.7FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Ẹtì 11am – 12pm | Kílààsì Sẹkọńdírì |
| Wazobia FM 95.1FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Rú 11am – 12pm | Kílààsì Pírámárì |
| Radio Gotel 91.1FM Yola | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Rú 11am – 12pm | Kílààsì Sẹkọńdírì |
| Radio Lagos 107.5FM | Ọjọ Ajé sí Ọjọ Bọ 9am – 11.55am | Kílààsì Pírámárì |
| Peace FM 102.5FM Borno | Ọjọ ìsẹgun àti Ọjọ Rú 09:30am-10:30am | Kílààsì Pírámárì |

Àkíyèsí:

- Ọpọ nínú àwọn ètò orí rédíò yìí ń wáyé lásìkò tí ilé-ẹkọ wà ní títì pa láàrin oṣù kẹta sí oṣù kẹwàá ọdún 2020. Ìgbàgbọ wa ni pé ọ pọ nínú wọn yóó tẹsíwájú lórí afẹfẹ káàkiri ilé-iṣẹ rédíò títí di òní.
- Wazobia FM ń ṣe iṣẹ ni Abuja, Kaduna, Jos, Minna, Lafia àti Suleja


Nísinsìnyí mo ti rí bí Bibian àti Bolanle ṣe ń kọ ẹkọ ní ilé. Èmí náà ní láti lo rédíò bàbá láti gbọ ẹkọ yìí?


E káàbọ sí ìkẹkọọ orí afẹfẹ FM. Orúkọ mi ni Sisi Nene, àti pé ẹkọ ti òní ni ẹkọ ìpìlẹ sáyẹnsì “Basic Science”, àkọlé ẹkọ ti òní ni “Hygiene”
Má gbàgbé láti pe 07099887766 ní ìparí ẹkọ láti bèèrè ìbéèrè. A ó pèsè ìdáhùn lẹsẹkẹsẹ.
Èyí dabí ẹni yéni ju tí kíláàsì lọ! Màá sọ fún bàbá kí wọn bá mi ra rédíò tèmi ki n lè tẹsíwájú nínú kíkọ ẹkọ ni ilé.

# ÌFỌWỌ́SÍ

## Onígbọ̀wọ́ iṣẹ́ àgbéṣe

## ALÁBÀÁṢEPỌ̀ IṢẸ́ ÀTI OLÙFỌWỌ́SOWỌ́PỌ̀

**ÀKÍYÈSÍ**

Àgbékalẹ̀ àti ìgbéjáde ìwé yìí wáyé láti ọwọ́ àjọ tí ó ń rí sí ìkẹ́kọ̀ọ́ ẹ̀kọ́ ìgbèríko Aid for Rural Education Access Initiative (AREAi) gẹ́gẹ́ bí àmújáde ohun-èlò ní abẹ́ àkóso Education Digital Equity Initiative èyí tí ilé-iṣẹ́ UK FCDO Prosperity Fund Digital Access Program dá sílẹ̀.

© Ẹ̀tọ́ àti àṣẹ lórí rẹ̀ jẹ́ ti Aid for Rural Education Access Initiative (AREAi).